# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**Oṣù Kéjìlá, Ọdún 2024**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**àti**

**Ìsìn Ifòróróyàn**

## OṢÙ KEJÌLÁ, ỌDÚN 2024 – AGBÁRA GBỌDỌ PARỌ ỌWỌ

## ÀWỌN ORIN ÌBẸ̀Ẹ̀RẸ̀

1. Orísun igbàlà kíkún! Orísun igbàlà kíkún!
Sí sílẹ̀ fún gbogbo wa,
Lát’Ọ̀dò Olùgbàlà wà,
Ló nṣàn yí gbogb’ayé ká;
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ìsun igbàlà kíkún.

2. Ìran ológo li èyí
Ìsun ìwẹ̀nùmọ́ nṣàn,
Ó nwẹ gbogbo abàwọ́n nù,
Ti ìdálẹ́bi ẹsẹ̀,
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ẹ̀jẹ̀ tí nwẹ̀ mọ́ láúláú.

3. Ìsun ijìnlẹ̀ ìfẹ́ Rẹ
Nṣàn ní inú ọkàn wa;
Ó nwẹ gbogbo erò aìmọ́,
K’a lè wà láílàbàwọ́n,
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ìsun igbàlà kíkún.

4. Ìsun iyè aìnìpẹ̀kùn,
Láti ọ̀run nṣàn sí wa,
Ọlọ́run dàpọ̀ pẹ̀lú wa,
Idàpọ̀ t’ó dùn jùlọ;
Ó nṣàn síbẹ̀,

Ìsun igbàlà kíkún.

5. Àníyàn àti ìyèméjì, òkùnkùn òn ‘bànújẹ́,
Ẹ̀rù àti ẹkún kì íṣe t’èmi mọ́,
‘Gbàgbọ́ kò mọ òkùnkùn ọ̀la,
Tor’Ólúgbàlà mi ti lọ síwájú,
Ìsun ìgbàlà kíkún, ó kún títí láíláí

1. Mo jẹ́ àlejò àt’aṣáko
Nín’òkùnkùn ẹ̀ṣẹ̀ ni mo nrìn
Jésù Olùṣágùntàn wá mi rí
Nísì mo wà lọ́nà s’ílé

**Ègbè:**
Nítòtọ́ ire at’ànú yó jẹ̀ tèmi
Ní gbogbo ọjọ́ ayé mi
Nítòtọ́ ire at’ànú yó jẹ̀ tèmi
Ní gbogbo ọjọ́ ayé mi.

2. Ó tu ọkàn mi lára nín’arẹ̀
Ó nfún mi lókun lọ́jọjọ́
Ó nsìn mí lọ sípa omi’yè
Ó sì ntọ́ ṣíṣẹ̀ mi kọ̀kan

3. Gbàtí mo nrìn ní àfonífojì
Olùgbàlà yó pẹ̀lú mi
Yó sì f’ọwọ́ agbára Rẹ̀ tọ́ mi
Sí ibùgbé lókè ọ̀run.

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, gbogbo àsọtẹ́lẹ̀ òdì tó lòdì sí ayé mi yóò padà sọ́dọ̀ àwọn tó ran-an lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo àsọtẹ́lẹ̀ sátánì fún ìpele mi t'ókàn, mo sọ ọ́ di asán àti òfo lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Bí mo ṣe n kópa nínú ètò yìí lónìí, mo gba agbára láti lọ sí ìpele mi t'ókàn, ní orúkọ Jésù.
4. Olúwa yóò jẹ́ kí àwọn ọgbọ́n fún alàjá tuntun sọjí nínú ayé mi lónìí, ní orúkọ Jésù.
5. Olúwa yóò mí ìmísí àwọn ohun tuntun sínú ayé mi lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Lónìí, nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ògo mi yóò farahàn, àti pé, gbogbo òkè iṣòro mi yóò pòórá, ní orúkọ Jésù.
7. Lónìí, Olúwa yóò dáhùn àwọn àdúrà mi gẹ́gẹ́ bí Ó dáhùn gbogbo ẹ̀bẹ̀ àdúrà Jábésì, ní orúkọ Jésù.

## **ÀDÓ ỌRỌ̀ NÁÀ**

**Ìsáíàh 43:18, 19:** Ẹ máṣe rántí nkan ti ìṣájú mọ́, àti nkan ti àtijọ́, ẹ máṣe rò wọ́n. Kíyèsí i, èmi ó ṣe ohun tuntun kan; nísisìyí ni yóò hù jáde; ẹ̀nyin kì yóò mọ̀ ọ́ bí? Lótọ̀, èmi ó la ọ̀nà kan nínú agìnjù, àti odò lí àṣálẹ̀.

**Fílíppì 3:12-14:** Kì íṣe pé ọwọ́ mí tẹ̀ ẹ́ ná, tàbí mo ti di pípé: ṣùgbọ́n èmi nlépa nṣó, bí ọwọ́ mi yóò lè tẹ èrè nà, nítorí èyití a ti dì mí mú pẹ̀lú, láti ọ̀dọ̀ Krístì Jésù wá. Ará, èmi kò ka ara mi sí ẹnití ọwọ́ rẹ̀ ti tẹ̀ ẹ́ ná: ṣùgbọ́n ohun kan yì li èmi nṣe, èmi ngbàgbé àwọn nkan tí ó wà lẹ́yìn, mo sì nnàgà wo àwọn nkan tí ó wà níwájú. Èmi nlépa láti dé òpin iré-ìje nì fún èrè ìpè gíga Ọlọ́run nínú Krístì Jésù.

**1 Pétérù 5:6:** Nítorínà, ẹ rẹ ara nyín sílẹ̀ lábẹ́ ọwọ́ agbára Ọlọ́run, kí òn kí ó lè gbé nyín ga lí àkokò.

**Òwe 3:5-6:** Fí gbogbo àyà rẹ gbẹ́kẹ̀lẹ́ Olúwa; má sì ṣe tẹ̀ sí ìmọ̀ ara rẹ. Mọ̀ ọ́ ní gbogbo ọ̀nà rẹ: òn ó sì ma tọ́ ipa-ọ̀nà rẹ.

**Rómù 12:2:** Kí ẹ ma sì da ara nyín pọ̀ mọ́ ayé yì: ṣùgbọ́n kí ẹ paradà láti di tuntun ní ìrò-inú nyín, kí ẹ̀nyin kí ó lè rí ìdí ìfẹ́ Ọlọ́run, tí ó dára, tí ó sì ṣe ìtẹ́wọ́gbà, tí ó sì pé.

**Hébérù 10:24-25:** Ẹ jẹ́ kí a yẹ ara wa wò láti ru ara wa sí ìfẹ́ àti sí iṣẹ́ rere: Kí a má ma kọ ìpéjọpọ̀ ara wa sílẹ̀, gẹ́gẹ́ bí àṣà àwọn ẹlòmíràn; ṣùgbọ́n kí a ma gba ara ẹni níyànjú: pẹ̀lúpẹ̀lú bí ẹ̀nyin ti ri pé ọjọ́ nì nsúnmọ́ etílé.

**Jeremíàh 29:11** Nítorí èmi mọ̀ ìrò tí mo rò sí nyín, li Olúwa wí, àní ìrò àláfíà, kì sí íṣe fún íbi, láti fún nyin ní ìgbà ìkẹyìn àti ìrètí.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

### ÌJẸ́WỌ́ - ORIN DÁFÍDÌ 91

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Olúwa, fún mi ní ọkùnrin inú tuntun bí a bá ti ṣíminípò-padà, ní orúkọ Jésù.
4. Olúwa, fí òróró yàn mí láti gbàpadà àwọn ọdún tí mo ti fi ṣòfò ní gbogbo agbègbè ayé mi, ní orúkọ Jésù.

5. Olúwa, bí mo bá wà lẹ́yìn ní agbègbè ayé mi ìyówù, rómilágbára láti gbàpadà gbogbo ànfàní àti àwọn ọdún tí mo ti fi ṣòfò, ní orúkọ Jésù.
6. Agbárakágbára tó wí pé nkò ní lọsíwájú, gba ìmúso, ní orúkọ Jésù.
7. Agbárakágbára tó fẹ́ fimí sínú aìní láàrín ọ̀pọ̀ yanturu, kú, ní orúkọ Jésù.